Ko si ninu ọmọniyan to jẹ musulumi ti irun ọran-anyan kan wa ba a, ti o wa ṣe aluwala rẹ daadaa ati ipaya rẹ ati rukuu rẹ, afi ki o jẹ ipa ẹṣẹ rẹ fun nnkan ti o ṣíwájú ninu awọn ẹṣẹ, niwọn igba ti ko ba mu ẹṣẹ nla wa, gbogbo igba si ni ìyẹn maa ri bẹ́ẹ̀

Lati ọdọ 'Uthman- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Mo gbọ́ ti ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe: "Ko si ninu ọmọniyan to jẹ musulumi ti irun ọran-anyan kan wa ba a, ti o wa ṣe aluwala rẹ daadaa ati ipaya rẹ ati rukuu rẹ, afi ki o jẹ ipa ẹṣẹ rẹ fun nnkan ti o ṣíwájú ninu awọn ẹṣẹ, niwọn igba ti ko ba mu ẹṣẹ nla wa, gbogbo igba si ni ìyẹn maa ri bẹ́ẹ̀".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe dajudaju ko si ninu musulumi kan ti asiko irun ọran-anyan maa wọle ba a ti o si ṣe aluwala rẹ daadaa ti o si pe e, lẹyin naa o n paya nibi irun rẹ pẹlu pe ọkan rẹ ati awọn orikee rẹ gbogbo rẹ dojukọ Ọlọhun ti wọn n ranti titobi Rẹ lori irun, O si pe awọn iṣẹ irun gẹgẹ bii rukuu ati iforikanlẹ ati eyi ti o yàtọ̀ si i, afi ki irun yii jẹ ipa ẹṣẹ rẹ fun nnkan ti o ṣíwájú ninu awọn ẹṣẹ kekere, niwọn igba ti ko ba ti da ẹṣẹ nla kan ninu awọn ti o tobi ninu awọn ẹṣẹ, ati pe ọla yii ma maa lọ bẹẹ pẹlu lilọ igba ati nibi gbogbo irun.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/6254